# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Adota: Osu kejila Ojo kewa, 2017**

**Akori oro: Okuta ikosile** – Apa keji

**Eko kika: Ise awon Aposteli 4: 1-12**

Ao tesiwaju ninu eko yi pelu awon idi ti ijeki awon enia ma ko Oluwa, ati awon oro Re ati awon eni-mimo sile. A ntesiwaju lati ibiti a ti duro.

**Awon idi ti a fi nko Oluwa, ati awon oro Re ati awon eni-mimo sile**
Ao soro nipa bi awon enia ti won lero wipe awon gbon ninu aiye ti nko Oluwa, ati awon oro Re ati awon eni-mimo sile.

**Aini ogbon ati imo:** Opo enia ninu aiye loni ni won lero wipe awon gbon je asiwere. Awon wonyi ma njeki iise ati idajo won da lori ogbon aiye; nipa bayi won a si ko Oluwa, ati awon oro Re ati awon eni-mimo sile. Ohun kan ti awon wonyi gbagbe ni wipe ogbon aiye yi asiwere ni niwaju Olorun. Ayafi ti won ba fi ogbon ati imo Olorun kun irin-ajo won ninu aiye yi; bibeko asiwere ni won **1 Korinti 3: 19.** Mase gba Satani laaye lati tan o, wipe o kun fun ogbon; nipa kiko Oluwa ati awon oro Re ati awon eni-mimo sile; nitoripe ogbon Olorun koni ko Oluwa ati awon eni-mimo sile tabi ki o lodi si won. Nitori idi eyi ni Bibeli se wipe "A ke awon enia mi kuro nitori aini imo: nitori iwo ti ko imo sile, emi o si ko o, ti iwo ki yio se alufa mi mo; niwon bi iwo ti gbagbe ofin Olorun re, emi pelu o gbagbe awon omo re." **Hosea 4: 6.** Mase ko imo ati ofin Olorun sile, sugbon fa won mo'ra; ki Olorun maba ko o lati je alufa Re, ki o si se alai-nani awon omo re. Nitorina, "Bi o ba ku ogbon fun enikeni, ki o bere lowo Olorun, eniti ifi fun gbogbo enia li opolopo, ti ki isi iba-ni-wi; ao si fifun u." **Jakobu 1: 5.** Bi enikeni ba se alaini ogbon, ki o bere lowo Olorun ti ifi ogbon funni, eyiti iba fi ko Oluwa ati awon eni-mimo sile.

**Isote:** Isote je okan lara awon iwa enia, eyiti o ma nmu ipalara wa ni opolopo igba sinu aiye awon olote. Ibi nikan ni enikeni ti o je olote ma nwa kiri, besini awon asebi tabi olubi enia a ma lepa isote si Olorun ni gbogbo igba. Idi niyi ti Iwe mimo se wipe "Eni-ote a ma wa kiki ibi kiri; nitorina iranse ika li ao ran si i." **Owe 17: 11.** Nitorina, iwo ko gbodo sote si Oluwa tabi ki o ko awon eni-mimo Re sile. Mase dabi Kora, Datani ati Abiramu ti won sote si Oluwa, ti won si ko Mose lati je asiwaju won **Numeri 16: 1-3.** Ko eko lati ara asise oba Saulu, eyiti o muki Samueli so awon oro wonyi si oba: "Nitoripe isote dabi ese afose, ati agidi gege bi iwa buburu ati iborisa. **Nitoripe iwo ko oro Oluwa, on si ko o li oba.**" **1 Samueli 15: 22-23.** Mase ko oro Oluwa, bi ko tile ni itumo li eti re tabi ki o mu ogbon lowo/dani si o gegebi enia;

nitoripe "Ero mi ki ise ero nyin, beni ona nyin ki ise ona mi" li Oluwa wi **Isaiah 55: 8-9.**

**Agidi:** Agidi je iwa ti o gbile gidigidi larin awon enia ninu aiye. Agidi je okan lara awon iwakiwa, ti ko se itewogba ni iwaju Olorun. Gbogbo alagidi enia jina si ododo; awon wonyi jina si idurosinsin, beni won ko si kun oju osunwon ni iwaju Olorun. A kowe re wipe "Gbo ti emi, enyin alagidi okan , ti o jina si ododo:" **Isaiah 46: 12.** Niwon igbati awon alagidi enia jina si ododo, Olrun ma nfi won sile fun lile aiya won tabi lati lepa agidi okan won; awon wonyi yio si ma rin ninu ero ara won **Orin Dafidi 81: 12.** O ko gbodo je alagidi, tabi ki o ko Oluwa sile, bi o ko ba fe rin ninu ero ara re; sugbon gboran, ki o si tele oro Oluwa ni igbagbogbo. Mase se afarawe oba Farao eniti tinu-mi- ni-mase jeki o wipe "Tali Oluwa ti emi o fi gba ohun re gbo lati je ki Israeli ki o lo? Emi ko mo Oluwa na, beli emi ki yio je ki Israeli ki o lo" **Eksodu 5: 2.** Farao se agidi, o si ko jale lati jeki Israeli lo: nitorina, Oluwa se awon ise ami ati iyanu ti o se ipalara fun awon enia ati awon eranko ni ile Egipti.

**Ife-inu lati ri bi awon keferi:** Ni ode oni, opolopo awon kristiani ni won ni ife-inu lati ri bi awon keferi, won ti gbagbe wipe awokose ni awon ise; awon ni o ye ki won ma fi ipinle rere le'le fun awon keferi lati tele e. Akainiye kristiani ni won ko ranti wipe awon ni iran ti a yan, olu-alufa, orile-ede mimo, enia oto **1 Peteru 2: 9.** Etise ti o fi ni ife-inu lati soro, lati wo aso, lati hu iwa ati lati gbe igbe-aiye bi awon keferi? Nigbati Bibeli jeri wipe awon keferi yio wa si imole re, ati awon oba si titan yiyo re **Isaiah 60: 3.** Nitorina, pa ife-inu ti o nfe ki o dabi awon keferi run, ma si se ko iwa awon keferi. Mase ko iwa ati ise awon keferi oniwa-kiwa ti won ma nwo awon irawo ati awon ise-owo Oluwa lati soro nipa ojo-iwaju **Jeremiah 10: 2.** Fun idi eyi mase dabi awon omo Israeli ti nwon da ara won po mo awon keferi , ti nwon si ko ise won ni ona ti o mu ki won ko Oluwa ati awon oro Re ati awon eni-mimo re **Orin Dafidi 106: 35.** Ya ara re kuro ninu aiye, mase huwa bi awon keferi, ki awon enia le ri daju pe o ko ni ife-inu lati so ara re di aimo; bikosepe o je mimo gege bi ase Olorun **Lefitiku 19: 2.**

## O ni lati jiya ki o to di "okuta ikosile"

Enikeni ti o ba fe lati di "okuta ikosile" ni lati gbaradi fun ijiya ki o ba le se aseyori. Idi niyi ti Jesu Kristi Oluwa se wipe "Alabukun-fun li enyin, nigbati nwon ba nkegan nyin, ti nwon ba nse inunibini si nyin, ti nwon ba nfi eke soro buburu gbogbo si nyin nitori emi. E ma yo , ki enyin ki o si fo fun ayo: nitori ere nyin po li orun: beni nwon sa se inunibini si awon woli ti mbe saju nyin" **Matteu 5: 11-12.** O ni lati jiya awon nkankan ki o to di okuta ikosile, ki o ba le di eni-ibukun ninu aiye, ki a si tun fun o ni ere ni orun.

**Asotele nipa Jesu Kristi Okuta Ikosile:** Iwe Isaiah wipe "A kegan Jesu Kristi , a si ko o lodo awon enia, eni –ikanu, ti o si mo ibanuje: o si dabi enipe o mu ki a pa oju wa mo kuro lara re; a kegan re, awa ko si ka a si." **Isaiah 53: 3.** Bi awon enia ba le kegan Jesu Kristi ti won si ko o, ko si eniti awon enia ko le ko sile. Bi Jesu Kristi ba jiya, ti o si mo ibanuje, ko si eniti ko ni jiya, ki o si ri ibanuje lati di okuta ikosile. Bi awon enia ba kehin si Jesu Kristi, ti won ko si ka si i; mase lero wipe awon enia yio wo odo re tabi won yio bojuto o, nitoripe o nse awon ohun ti o to.

**Okuta Ikosile se aini awon ohun amaiye-rorun:** Jesu Kristi se alaini awon ohun amaiye-rorun nigbati o mbe ninu aiye. Ni ojo kan Jesu sun ni Betani, nigbati o npada bo si Jerusalemu, ebi npa a. O ri igi opoto kan, sugbon ko ni eso bikose kiki ewe **Matteu 21: 18-19; Mark 11: 11-13.** Ni ojo kan Jesu nlo si Galili, o si gba ilu kan ti a npe ni Sikari koja. O ti re Oluwa, beni ebi si npa a. O duro ni ibi kanga Jakobu, O so fun obinrin ara Samaria ti o wa lati fa omi wipe " Fun mi mu" nitori awon omo-ehin re ti lo si ilu lo ira onje **Johannu 4: 3-8.** Bi otilejepe Jesu Kristi ni agbara ati ase eyiti o lo lati bo egberun merin enia; pelu isu akara meje ati eja kekeke die. Ko lo agbara yi lati fi kun ikun re nigbati ebi npa a: toripe o mo wipe on ni lati se irubo awon nkankan **Matteu 15: 32-38.** Iwo na ni lati se irubo tabi ki o jiya awon nkankan ki o to le di okuta ikosile.

Nigbati okunrin akowe kan so fun Jesu wipe "Olukoni, emi o ma to o lehin nibikibi ti iwo nlo" Jesu dahun wipe "Awon kolokolo ni iho, ati awon eiye oju orun ni ite; sugbon, Omo-enia ko ni ibi ti yio fi ori re le" **Matteu 8: 18-20.** Bi Jesu se je oloro to ninu ijoba re, ko ni ile akogbe nigbati o wa ninu aiye: nitorina mase jeki esu fi ohun meremere aiye yi di o lowo lati di okuta ikosile.

**Imuse asotele ati oro ohun ti yio sele ti Jesu Kristi wi:** Asotele nipa Jesu Kristi wa si imuse; nigbana ni o soro nipa ijiya, ati ikosile, ati iku, ati ajinde re. "O si bere si ko won pe, Omo-enia ko le saima jiya ohun pupo, ao si ko o lati odo awon agbagba ati awon olori alufa, ati awon akowe, ao si pa a, lehin ijo meta yio si jinde" **Mark 8: 31.** Mase foiya, nitoripe ijiya tire le ma to iru ti Jesu; sugbon sibe o ni lati jiya ki o to le di okuta ikosile: ki a ba le bukun fun o li aiye yi, ki a si tun fun o li ere li orun. Ohun kan ti o ni lati mo ni wipe, bi o ba jiya nitori Jesu Kristi ati awon oro re; ao se o logo pelu re, beni iwo o si ba joba titi-lai ninu ijoba re li orun **Romu 8: 17.**

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose kokanleladota: Osu kejila Ojo ketadinlogun, 2017**

**Akori oro: Okuta ikosile** – Apa keta

**Eko kika: Ise awon Aposteli 4: 1-12**

Eko yi ntesiwaju, nigbati ao soro lori awon eto-igbese ti isoni di okuta ikosile. Niwon igbati okan lara ohun ti o daraju ti o le sele si eda-enia ni ki o di "okuta ti awon omole ko sile ti o di pataki igun ile." Nitorina, awa onigbagbo ni lati se akitiyan lati di "okuta ikosile".

### Awon eto-igbese ti a nilo ki enia to le di okuta ikosile

Opolopo ni awon eto-igbese ti a gbodo gbe ki a to di okuta ikosile, sugbon koko larin awon igbese yi ni pe, a ni lati mura-tan tabi gbaradi fun iponju, inunibini ati wahala. Nitorina, e mase jeki o ya yin lenu, tori iyonu-kiyonu ti o nsele lati dan igbagbo yin wo ki ise ohun ajoji. E ko gbodo ka idanwo-kidanwo ti e nla koja gegebi enipe ohun ajoji ni o de ba yin; sugbon e yo, nitori e je alabapin ninu iya Kristi, ki e ba le ni ayo pupo nigbati a ba fi ogo re han **1 Peteru 4: 12-13.**

**Iponju, inunibini ati wahala:** A ni lati mo wipe gbogbo enia ti o ni inudidun lati lepa ododo, ti won si ti pinnu lati gbe igbe iwa-bi-Olorun ninu Kristi ni lati farada iponju ati inunibini. Awon wonyi yio jiya nitori esin ati igbagbo won **2 Timoteu 3: 12.** O ni lati gbaradi fun inunibini, bi o ba fe gbe igbe-aiye-mimo ati igbe-aiye-olufokansin ninu Kristi Jesu lati di "okuta ikosile". "Nitori inu eyi li a pe nyin si: nitori Kristi pelu jiya fun nyin, o fi apere sile fun nyin, ki enyin ki o le ma to ipase re" **1 Peteru 2: 21.** Nigbakugba ti o ba njiya nitori ododo, eni ibukun ni o: Nitorina, mase foya iberu awon aninilara re ati wahala won. Ko si wala okan re, wipe nigbakugba ti o ba njiya nitori ti o se ohun tito, Olorun yio fun o ni ere: nitorina, mase jaiya nitori iberu awon ota re, beni mase kominu nitori ihale awon asoro-odi tabi awon alatako re **1 Peteru 3: 14.** O dara bi o ba se afarawe awon aposteli ti won fi tayotayo kuro niwaju ajo igbimo, nitori ti a ka won ye lati jiya nitori oruko Jesu Kristi **Ise awon aposteli 5: 41.** Fun idi eyi, ma yo ayo-igbala ni igbagbogbo ti o ba jiya nitori oruko Kristi lati di "okuta ikosile".

**Sora fun awon ofin enia, ilana enia ati awon ofin atowodowo:** Akainiye enia ninu aiye loni ni won nfi enu won fa mo Olorun, ti won si nfi ete won bu ola fun u; sugbon ti okan won jina si Olorun: iberu ti won ni si Olorun ki ise ojulowo,

nitoripe nipa ilana-enia ni. A kowe re pe, "Oluwa wipe 'Niwon bi awon enia yi ti nfi enu won fa mo mi, ti nwon si nfi ete won yin mi, sugbon ti okan won jina si mi, ti nwon si beru mi nipa ilana enia ti a ko won'" **Isaiah 29: 13.** Bi o ba fe je okuta ikosile, o ni lati sin Olorun tokantokan; ki ise nipa ori-ahon tabi karimi. Mase sin Olorun nipase ofin-enia tabi ofin atowodowo, bi o ba fe jogun iye ainipekun. Mase darapo mo awon ogoro enia ti won ni ona alumo-koroyi ti won fi nko ofin Olorun sile; ti won si nda ofin Re nu, ti won si tun nyi ofin Olorun po; nitori ofin-enia, nitori asa, ati nitori ofin atowodowo **Mark 7: 9.** Mase ko ipa ninu kiko ofin Olorun sile, tabi gbigba ofin Olorun si egbe kan nitori asa, ki o ba le dara fun o. Isin enikeni ti o ba so ofin Olorun di ofifo, nitori ati gbe asa ro, tabi ki asa le gbile, yio je lori asan ati imule-mofo. Bibeli wipe "Sugbon lasan ni nwon nteriba fun mi, nwon nfi ofin enia koni fun eko" **Matteu 15: 9; Mark 7:7.** Bi o ko ba fe ki Olorun fagile isin re, mase koni ni ofin enia bikose ofin Olorun. Bi o ba fe ki isin re se itewogba ni iwaju Olorun, mase ko ofin Re sile nitori ofin atowodowo. Mase pa ofin Olorun ti lati gbe asa laruge **Mark 7: 8.** Sora, ki o ma si se aibikita tabi ainani ofin Olorun, nitori ogbon/ona ati fi ofin atowodowo dipo/ropo ofin Olorun.

O ko gbodo dabi alaimoye omode, ti a nfi afefe-iji gba kiri nipa eko titun. O ko gbodo jeki awon enia lo agbari, lati fi iro ti o rarajo/farape otito tan o je. Iwe mimo wipe "Ki awa ki o mase je ewe mo, ti a nfi gbogbo afefe eko ti siwa ti sehin, ti a si fi ngba kiri, nipa itanje enia, nipa arekereke fun ogbonkogbon ati muni sina" **Efesu 4: 14.** Kiyesara fun awon eko adamodi, ti awon enia ti won ni ogbon arekereke fi ntani-je. Sora fun ogbon ti awon enia nlo, nitori ere ti ara won, lati fi si awon elomiran lona. Mase jeki a fi imo ati oro-didun ti njade nipase ero-enia ati agbara-aiye, ti ki ise lati odo Jesu Kristi di o ni igbekun. Bibeli wipe "E ma kiyesara ki enikeni ki o mase fi imo ati etan asan di nyin ni igbekun, gegebi itan enia, gegebi ipilese eko aiye, ti ki ise bi ti Kristi" **Kolosse 2: 8.** Ri daju pe, a ko di o ni igbekun, nipase ipilese eko aiye ati etan asan. Fun idi eyi, mase fiyesi itan ati alo ati awon ofin, ti awon enia ti won ko otito sile, ti won si kehin si otito gbe kale. O ko gbodo fetisi itan asan, ati ofin awon enia ti won ti yipada kuro ninu otito **Titu 1: 14.** Akoko tito, dekun ati fiyesi itan asan, ati ofin awon enia ti won ti ko otito sile, sugbon teramo kiko eko Bibeli mimo.

**Ba awon alarekoja wi, ki o si ma so otito:** Ipokipo ti o le wa, ma so otito ni igba gbogbo, ma ba awon obayeje-enia wi, ki o si ma tu awon ti anilara ninu. A kowe re pe "Ko lati se rere; wa idajo, ran awon eniti anilara lowo, se idajo alainibaba, gba ejo opo wi" **Isaiah 1: 17.** Enikeni ti o fe lati di okuta ikosile gbodo ni awon

iwa daradara ti a menuba yi, bikosebe, onitohun ntan ara re ni. O ni lati wasu Ihinrere, o ni lati muratan lati wasu oro yi, nigbati aye wa fun o ati nigbati aye kosi fun o; o ni lati wasu nigbati ojurere mbe fun o, ati nigbati kosi; o ni lati wasu nigbati o wo ati nigbati ko wo. O ni lati to awon ti won ntase-agere nipa ilana ati nipa iwa, si oju ona. O ni lati kilo fun awon ti ndese, ki o si ba-won wi lati ronupiwada. O ni lati gba awon ti ndagba ninu emi ati eko-otito niyanju pelu suru ati ipamora **2 Timoteu 4: 2.** Mase gbagbe lati baniwi, lati toni sona, ati lati se ikilo, ki o maba pin ninu ebi won. Mase gbagbe lati ba awon ti won sako kuro ni ona otito wi, ki o si se ikilo ki won ba le se atunse; ki won si le ye koro ni igbagbo **Titu 1:13.** Nigbakugba ki o ba ko-firi wipe awon enia nya kuro ninu otito, o ni lati ba-won wi gidigidi, ki won le ni igbagbo ti o lagbara. Ranti wipe ni igbakugba ti o ba nba awon enia wi, ti o si nna won, o nse eyi nitoripe o ni ife won ni: atipe o ko fe ki won segbe; ni Bibeli wi **Ifihan 3: 19.**

**Mase se ojusaju, lo idajo tabi gba abetele:** Ara ninu Oluwa, e ko gbodo se ojusaju ninu ohunkohun: beni iwo ko gbodo gbe talaka li ejo re, ni Bibeli wi **Eksodu 23: 3.** Nitorina, e mase se ojusaju ninu ohun gbogbo ti e ba nse, nitoripe, "Oluwa Olorun nyin, Olorun awon olorun ni ati Oluwa awon oluwa, Olorun titobi, alagbara, ati eleru, ti ki ise ojusaju, beni ki igba abetele" **Deuteronomi 10: 17.** Fun idi eyi, mase lo idajo tabi pa idajo da. O ko gbodo se ojusaju tabi gba abetele, nitoripe abetele ni njeki ologbon di-oju si otito, besini a si muki ipinnu eni iwa-bi-Olorun tase. Iwe mimo wipe "Iwo ko gbodo lo idajo; iwo ko gbodo se ojusaju enia: beni iwo ko gbodo gba ebun; nitoripe ebun ni ifo ologbon li oju, on a si yi oro olododo po" **Deuteronomi 16: 19.** Torina, mase pa idajo da, mase gba abetele tabi se ojusaju ninu gbogbo adawole re.

Awon asiwaju ati awon ti mbe ni ipo alase ko gbodo ri ara won bi olorun; tabi ki won wu iwakiwa si elomiran, nitori ipo won. Iwa won ko gbodo mu ipaiya ba awon awujo enia: won ko gbodo huwa 'tani ma mu mi": tabi huwa "ninu agbara ni a gbagbo": tabi huwa "kise pe a mbe ni ijoba nikan agbara mbe lowo wa": sugbon, won ni lati beru Olorun ninu gbogbo adawole won. Bibeli wipe "Nje nisisiyi, je ki eru Oluwa ki o wa lara nyin, e ma sora, ki e si se e; nitoriti ko si aisedede kan lodo Oluwa Olorun wa, tabi ojusaju enia, tabi gbigba abetele" **2 Kronika 19: 7.** E se ijoba ati idajo pelu otito: nitori Olorun ko fe lilo idajo, ati ojusaju, ati gbigba abetele. Awon wonyi ko gbodo gbagbe pe Olorun yio ba-won wi, bi won ba se ojusaju ni ikoko. Niwon igbati Olorun mo ohun gbogbo, yio je won niya fun gbogbo iwakiwa, ti won ba hu ni ikoko **Jobu 13: 10.** Olorun ki ise ojusaju, beni aidogba kosi lodo re; yio se idajo olukuluku bakanna ni, iru eniti o wu ki o je. Ni

kukuru, ojusaju enia ko si lodo Olorun **Romu 2: 11.**

**Iforiti ati ifarada:** Ri daju pe o fe omonikeji re, nitoripe ife a ma farada ohun gbogbo, lai-ro ohun ti yio ti idi re jade; a ma gba ohun gbogbo gbo, nipa wiwo ohun ti o daraju ninu enikankan; a ma reti ohun gbogbo, nipa diduro sinsin ni igba isoro; a ma faiyaran ohun gbogbo, ni alai-saare **1 Korinti 13: 7.** O ni lati foriti i, ninu ipokipo ti o ba wa, ki o ba le di okuta ikosile. Awon enia ti o yi o ka, le korira re nitori ajose re pelu oruko Kristi. Awon eda-enia le korira re, nitori oruko Kristi: sugbon bi o ba fi suru farada a, ti o si foriti titi de opin, ao gba o la **Mark 13: 13, Matteu 24: 13.** Bi o ba fe ki Oluwa so o di okuta ikosile, o ni lati foriti ohun gbogbo titi de opin. Fun idi eyi, o ni lati farada iponju, bi omo-ogun rere Jesu Kristi **2 Timoteu 2: 3.** Ranti wipe ni aisi iforiti, Jesu Kristi ko ni so o di alaba-pin iye ainipekun; ko sini tu o sile kuro lowo iku, nipa ti emi. Nitorina, o nilo iforiti, lati di okuta ikosile.

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

### Ose Kejileladota: Osu Kejila Ojo Kerinlelogun, 2017

### Akori oro: Okuta ikosile – Apa Kerin

### Eko kika: Ise awon aposteli 4: 1-12

Ao tesiwaju ninu eko yi nigbati ao menuba awon iyorisi kiko Oluwa, ati awon oro re, ati awon eni-mimo sile.

**Awon iyorisi kiko Oluwa ati awon eni-mimo sile**

Opolopo ni awon iyorisi ti yio deba awon enia ti won ko Oluwa, ati oro re, ati awon eni-mimo re sile.

**Kiko Olorun sile ati alai-ye fun iye ainipekun:** A ni lati koko mo wipe Olorun ma nran oro re si awa enia ki ale se atunse, tabi nitori ati kilo fun wa, nitori ewu ti mbo. Oro re ma njade si wa lati fi igbagbo wa mule, ati lati da abo bowa, ati lati pa wa mo laaye. A kowe re wipe "Oro re ni fitila fun ese mi, ati imole si ipa ona mi" **Orin Dafidi 119: 105.** Mase ko oro Oluwa ti a ran si o, lati to o si oju-ona ati lati da abo bo o; nitoripe, enikeni ti o ba ko o, ko ko enia, bikose Olorun, eniti o fun o ni Emi mimo re **1 Tessalonika 4: 8.** Nitorina, mase ko oro Oluwa sile, beni mase se alaibowo fun oro re; mase sa oro Oluwa ti si egbe-kan, nitoripe, enikeni ti o ba ko lati gbe igbe-aiye nipase ofin Oluwa, ko se aigboran si enia bikose si Oluwa: iru awon enia be ki yio lo lai-jiya. Ijiya iru awon enia wonyi ni pe won yio di alai-ye fun iye ainipekun. Fun idi eyi ni iwe mimo se wipe "Enyin li o to ki a ko so oro Olorun fun: sugbon bi e ti ta a nu, e si ka ara nyin si alai-ye fun iye ainipekun, wo o, awa yipada sodo awon keferi" **Ise awon aposteli 13: 46.** Mase ko oro Oluwa, bi o ba fe jogun ijoba orun. Niwon igbati enikeni ti o bati ko oro na, ti se idajo ara re gegebi alai-ye fun iye aiyeraye.

**Olorun yio ko won sile, yio si da won lebi:** A ni lati mo wipe awon eni-mimo ni a nran lati so oro-Olorun ti Oluwa ran siwa; bikosebe ohunkohun ti won ba nso yio lodi si eko Bibeli mimo. Nitorina, tetisile ki o gbo, beni ki o si tele oro Olorun ti a ran si o, nipase awon eni-mimo: nitoripe, enikeni ti Olorun ba ran ni iso oro Olorun **Johannu 3: 34.** Mase dabi awon Farisi ati awon amofin, ti won ko ife Olorun fun ara won; nipa kiko lati se iribomi lati owo Johannu-onitebomi. Awon wonyi pa ipinnu rere ti Olorun ni fun won ti si egbe-kan **Luku 7: 30.** O ko gbodo ko eto ti Olorun ni fun o, tabi ki o ko ipinnu rere ti o ni fun aiye re; ki Olorun maba pa o ti i, ki O si ko o. Bibeli wipe "Fa irun ori re, ki o si so o nu, ki o si sokun lori oke: nitori Oluwa ti ko

iran ibinu re sile, o si sa won ti" **Jeremiah 7: 29.** Mase ko oro ati eto ti Olorun ni fun o, bi o ko ba feki O ko o sile.

**Oju yio ti won, ao si pe won ni enia olokan-wiwo:** Awon enia ti won ko oro Olorun ati awon ti won je ologbon ninu won ni ao dojuti; won yio damu, ao si mu won sinu igbekun: nitoripe won ko oro Olorun. Iru ogbon tabi imo wo ni o ngbe ninu enikeni ti o ko oro Olorun, bikose ti satani? A kowe re pe "Oju ti awon ologbon, idamu ba won a si mu won: sa wo o, nwon ti ko oro Oluwa! Ogbon wo li o wa ninu won?" **Jeremiah 8: 9.** Iru ogbon wo ni ngbe ninu aiye re, ti o le mu ki o ko oro Olorun sile? Bi o ko ba feki a dojuti o, ki a si fi o sinu igbekun ninu were re; mase ko oro Olorun, ki awon enia maba pe o ni fadaka bibaje ati olokan-wiwo enia. Enikeni ti ko ba fe ki Oluwa ko on sile, ki a si pe e ni fadaka alai-niye-lori, ko gbodo ko oro Olorun. Bibeli wipe "Fadaka bibaje ni enia yio ma pe won, nitoriti Oluwa ti ko won sile" **Jeremiah 6: 30.** Bi o ko be fe ki awon enia pe o ni fadaka alai-nilari, mase ko oro Olorun ati awon iranse re.

**Won ki yio se aseyori tabi ni ifokan-bale:** A ni lati mo wipe, enikeni ti o ba ko Oluwa ti fi aye sile fun okunkun lati gbogun ti i. Ibanuje, ipayin-keke ati abamo yio si pa ago ti iru enia be. Awon ota yio si ma lepa iru enia be, nitoripe onitohun ti ko ohun-rere tabi gbe ohun-rere sonu **Hosea 8: 3.** Bi o ba fe ifokanbale, mase ko ohun-rere. Bi o ko ba fe ki awon ota ma lepa re, mase ko Oluwa ati awon eni-mimo; ki Oluwa maba ko iwo ati awon alanu/oluranlowo re sile. A ni lati mo wipe Oluwa yio ko awon ore tabi alabaro enikeni ti o ba ko Oluwa sile. Oluwa yio ko awon enia ti awon ti o ko Oluwa sile fi se igbekele won, ki won maba le se iranlowo fun onitohun, beni ki eniti o ko Oluwa sile maba ri ere lati odo won. Bibeli wipe "Loto iwo o kuro lodo re, iwo o si ka owo re le ori, nitori Oluwa ti ko awon onigbekele re, iwo ki yio si se rere ninu won" **Jeremiah 2: 37.** Bi o ba fe se aseyori ninu irinajo igbagbo, mase ko Oluwa ati awon eni-mimo sile.

## Awon ijiya fun kiko Oluwa sile

Ao soro nipa awon ijiya ti yio sele si awon enia ti won ko Oluwa ati awon eni-mimo sile, ninu awon ti a ko sinu Bibeli lati da awon enia ti won ni iru ero yi lekun.

**Kosi ona abayo:** Kosi ona abayo fun enikeni ti o gbe awon eko Oluwa awon omo-ogun sonu, ti o si nsoro-odi si awon oro Eni-Mimo Israeli. Kosi bi onitohun ti le lowo to, tabi ki o kawe to, tabi iru ipo ti o le wa lawujo ti yio lo lai-jiya. Kosi bi o ti wu kope to, ti yio mu onitohun bo lowo ijiya fun iwa-ibaje yi. A kowe re wipe "Nitorina bi ina ti ijo akeku koriko run, ti owo ina si ijo iyangbo; beni egbo won yio

da bi rira; itana won yio si goke bi ekuru; nitori nwon ti sa ofin Oluwa awon omo-ogun ti, nwon si ti gan oro Eni-Mimo Israeli” **Isaiah 5: 24.**

**Iparun ojiji yio wa sori won:** Iparun ojiji yio wa sori awon enia ti won ko gboran tabi tele oro Oluwa, sugbon ti won ko ofin Re sile. Ibi ti ise ere-iwa tabi ipinnu buburu won, yio si bori won gegebi ese Bibeli ti o wipe “Gbo iwo ile! wo o, emi o mu ibi wa si ori enia yi, ani eso ero inu won, nitori nwon ko fi eti si oro mi, ati ofin mi ni nwon ko sile” **Jeremiah 6: 19.**

**Ao je won niya ni orisirisi ona gegebi ikosile won:** Olorun yio je enikeni ti o ba ko on ati awon oro Re niya, gegebi asise won. Ni igba ti awon omo Israeli, a je won niya fun ogoji odun ninu aginju. Iwe mimo fi idi re mule pe a je won niya “Gege bi iye ojo ti enyin fi rin ile na wo, ani ogoji ojo, ojo kan fun odun kan, li enyin o ru ese nyin, ani ogoji odun, enyin o si mo iba ileri mi je” **Numeri 14: 34.** Kiyesara nitoripe ijiya ese tire le gbori/gbooro ju eleyi lo. Lotito ile ya enu re, o si gbe Kora, Datani ati Abiramu mi: ijiya tire le je ni ona miran, ti yio si se akoba fun o, ni gbogbo igba iwa-laaye re **Numeri 16: 30-32.** Mase se afojudi tabi dan Olorun wo, nipa kiko on ati awon oro re.

**Ao ko won sile, ao si paro won:** Olorun ko Saulu gegebi oba ni Israeli nitoripe o ko oro Oluwa. Eyi muki Samueli wi fun Saulu pe “Emi ki yio tun yipada pelu re mo nitoriti iwo ti ko oro Oluwa, Oluwa si ti ko iwo lati ma je oba lori Israeli” **1 Samueli 15: 26.** Bi Oluwa ba le ko oba akoko ti o je lori Israeli, kosi eniti Oluwa kole ko, fun kiko Oluwa ati awon oro re sile. A fi oba Dafidi ropo oba Saulu nigbati Oluwa pase fun Samueli lati fi ororo yan Dafidi. A kowe re pe, Oluwa si wi fun Samueli pe “Yio ti pe to ti iwo o fi ma kanu Saulu, nigbati o je pe, mo ti ko o lati ma joba lori Israeli? Fi ororo kun iwo re, ki o si lo, emi o ran o to Jesse ara Betlehemu: nitoriti emi ti ri oba kan fun ara mi ninu awon omo re” **1 Samueli 16: 1.** Ni idaniloju pe, kosi ohunkohun ti eniti o ko Oluwa ati awon oro re sile le se, ti a ko fini paro re.

**Won ki yio wo inu ile ileri:** Enikeni ti o ba ko Oluwa ati awon oro re ki yio de ile ileri, tabi ki o wonu ile imuse-ogo aiye re. Ijiya ti o lagbara-ju fun iru enia na ni wipe, onitohun ki yio wo Ile-ologo tabi ki o jogun ijoba orun/aiyeraye ayafi bi o ba ronupiwada. Idi niyi ti Bibeli fi se ikilo wipe “Nitoto nwon ki yio ri ile na ti mo ti fi bura fun awon baba won, beni okan ninu awon ti o gan mi ki yio ri i” **Numberi 14: 23.** A gbadura wipe Olorun yio darijin, yio si gbojufo awon asise ati ese ti o le muwa kuna/padanu ijoba ologo ti Baba wa orun.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

## Awon anfani

Opolopo anfani ni o wa fun awon enia ti won ko ko Oluwa, ati awon oro re ati awon eni-mimo sile. Ao menuba ninu awon anfani wonyi.

**Iwo ki yio se alaini:** Iwo ki yio ra-hun tabi se alaini awon ohun rere. Oluwa yio bojuto o, beni yio si pese awon ohun-kosemani fun o ni kikun; nitoripe iwo ko ko Oluwa sile, sugbon o nfi tokatokan wa a, o si gbekele e **Orin Dafidi 34: 10.**

**Iwo yio ma je isura awon keferi:** Ao pe o ni alufa Oluwa, awon enia yio ma bola fun o gegebi iranse Olorun Olodumare. Iwo yio je oro awon keferi, ati ninu ogo won ni iwo yio ma sogo. Iwo yio ma fela ninu oro won, beni okiki re yio tan kari aiye **Isaiah 61: 6.**

**Awon alagbara oba ati orile-ede ni yio te o lorun:** Awon enia yio fun o ni ohun ti o ba nfe, gegebi omo ti imu wara iya re, iwo yio mu ola ati oro lati odo awon oba; awon oba ati awon asiwaju/olori yio si te o lorun pelu ohun meremere **Isaiah 60: 16.**

**Iru-omo awon aninilara re yio wa ojurere re:** Awon omo awon aninilara re yio wa ni iteriba si iwaju re; gbogbo awon ti o ti ngan o, ati awon ti o korira re, yio te ara won ba sile li atelese re; won o si pe o ni eni ami-ororo Oluwa **Isaiah 60: 14.**

**Ojo awe re yio dopin:** Orun re ki yio wo mo, beni osupa re ki yio wokun; nitori Oluwa yio je imole ainipekun fun o, ojo awe re wonni yio si de opin **Isaiah 60: 20.**

**Iwo yio se ise ami ati iyanu:** Niwon igbati iwo ko ti ko Jesu Kristi sile, sugbon ti o gba a gbo; iwo yio se iru ise kanna ti Kristi se, beni iwo yio tun se awon ise ami ati iyanu ti o lagbara, ni Bibeli wi **Johannu 14: 12.**

**Ao da iru-omo re mo lawujo, ao si bowo fun won:** Ao mo awon omo re larin awon orile-ede agbaiye ati iru-omo re larin awon enia. Gbogbo eniti o ba ri won ninu ola-nla yio mo won, beni oye yio si ye won wipe awon eni-ibukun Olorun ni won. Gbogbo enia yio mo wipe iru-omo ti Oluwa ti busi, ni awon omo re ise **Isaiah 61: 9.**

**Iwo yio je ogo aiyeraye:** Lotito ni a ti ko o sile, ti a si korira re; Olorun yio so o di ogo aiyeraye ati ohun amuyangan-titilai. Iwo yio si je ayo iran-de-iran **Isaiah 60: 15.**

**Ao fi oruko titun pe o:** Awon orile-ede yio ri ododo ati idalare re ti o ti odo Olorun wa. Awon olori/asiwaju ni agbaiye yio ri ogo re, imole-ogo re yio si fo won loju nipa ti emi: beni ao si fi oruko titun pe o, eyiti yio ti enu Oluwa jade **Isaiah 62: 2.**

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose ketaleladota: Osu kejila Ojo kokanlelogbon, 2017**

**Akori oro: Okuta ikosile** – Apa karun

**Eko kika: Ise awon aposteli 4: 1-12**

Ao tesiwaju ninu eko yi, pelu oniruru apejuwe ti a menuba ninu Bibeli. Ao soro nipa bi Olorun ti se fi idalare fun awon eni-mimo Re, ti o si muki awon enia ti o ko nwon sile yipada lati ma wa ojurere won.

**<u>Awon apejuwe awon okuta ikosile</u>**

Ao bere awon apejuwe awon okuta ikosile pelu ogbontarigi, ati eni-akoko ti ise orisun gbogbo okuta ikosile. Enikan soso ti ise Oluwa awon oluwa, Oba awon oba ati Omo Alade-alafia ti ise Jesu Kristi ti Nazareti. Jesu Kristi Olugbala wa ni ibere ati opin awon eni-mimo ti awon enia kosile, nitoriti won se awon ohun daradara, ti o si se itewogba ni iwaju Olorun.

**<u>Ikosile Jesu Kristi ni Nazareti:</u>** Nigbati Jesu Kristi wa si ilu on tikara re, O nko awon enia ninu sinagogu. Enu ya awon enia, won si wipe "Nibo li okunrin yi ti mu ogbon yi ati ise agbara wonyi wa? Omo gbenagbena ko yi? Iya re ko a npe ni Maria? Ati awon arakunrin re ko Jakobu, Jose, Simioni ati Juda? Ati awon arabinrin re, gbogbo won ki o mba wa gbe nihinyi? Nibo li okunrin yi ti mu gbogbo nkan wonyi wa?" Beni won kose lara re, eyiti o muki Jesu wipe "Ko si woli ti o wa laili ola bikose ni ilu ati ni ile on tikarare" Nitorina, Jesu ko se opo ise agbara nibe, nitori aigbagbo won **<u>Matteu 13: 53-58, Mark 6: 1-5.</u>** Mase dabi awon ope ti won ko Jesu Kristi, sugbon faa-mo, ki o si fi emi-imore han si i, ni gbogbo akoko iwalaaye re.

**<u>Awon alase ati awon enia ko Jesu:</u>** Nigbati Jesu nkoni ni Kapernaumu, awon Ju nkun si i, nitoriti o wipe, "Emi ni onje ti o ti orun sokale wa." Nwon si wipe, Jesu ha ko eyi, omo Josefu, baba ati iya eniti awa mo? Etise wipe, Emi ti orun sokale wa?" **<u>Johannu 6: 41-42.</u>** Mase wa lara awon olori ati awon ti mbe ni ipo alase ti won ko Jesu sile. Awon onse, ati awon olori alufa, ati awon Farisi ko gbagbo ninu Jesu Kristi ati awon ise iyanu ti o se; nipase be, won ko o **<u>Johannu 7: 45-48.</u>** Anu ati ore-ofe Olorun ni o gbe o de ipo-ola ati ipo owo ti o wa lowolowo. Nitorina, mase ko Oluwa.

**<u>Ileto Samaria ko Jesu Kristi:</u>** Bi akoko ti nsunmo etile fun Jesu Kristi lati goke re orun, o gbe oju re gangan lati lo si Jerusalemu. O ran awon onse lo si iwaju re, si ileto Samaria lati pese sile de e, sugbon awon enia ileto na ko si gba a. Nigbana ni Jakobu ati Johannu wi fun Jesu pe, " Oluwa iwo ko je ki awa ki o pe ina lati orun wa, ki a si sun won lulu, bi Elijah ti se?" **<u>Luku 9: 51-54.</u>** O ko gbodo ko Oluwa gegebi awon alaigbagbo, sugbon gba a ni kikun, ki o si ma juba re.

**<u>A ko Olorun ati awon ikilo re:</u>** Asise ti o tobiju ti enikeni le se, ni ki o ko Olorun Olodumare ati awon oro Re sile. Ninu Bibeli awon omo Israeli se eyi, beni a je nwon niya, nwon si kabamo.

Nigbati Samueli di arugbo, awon agba Israeli to o wa, Nwon si beere fun oba, ti yio ma se alakoso lori won gegebi awon orile-ede miran; nitori awon omo Samueli ti ise onidajo ko fi otito rin irin-ajo. Oro yi buru loju Samueli, sugbon Oluwa sofun wipe "Gbo ohun awon enia na ni gbogbo eyi ti nwon so fun o: nitoripe iwo ki nwon ko, **sugbon emi ni nwon ko lati je oba lori won" <u>Samueli 8: 1-7.</u>** Nitorina, nibiti a ti nfi Saulu joba ni Mispa, Samueli so wipe "Enyin si ko Olorun nyin loni, eniti on tikara re ti gba nyin kuro lowo gbogbo awon ota nyin, ati gbogbo wahala nyin; enyin si wi fun u pe, beko, sugbon awa nfe ki o fi enikan joba lori wa. Nisisiyi e duro niwaju Oluwa nipa eya nyin, ati nipa egbe-gberun nyin" **<u>1 Samueli 10: 17-19.</u>** Nipa kiko Olorun sile, awon omo Israeli fi ara won fun laala gegebi awon orile-ede toku ninu aiye.

Awon omo Israeli ko ikilo ti Olorun ran si nwon lati owo woli Jeremiah, eyiti o wipe, Bayi ni Oluwa wi, "Sa wo o, emi npete ibi si nyin, emi si nse ipinnu kan si nyin, si yipada, olukuluku kuro ninu ona buburu re, ki e si tun ona ati ise nyin se rere". Nwon si wipe " Lasan ni: nitori awa o rin nipa ipinnu wa, olukuluku yio si huwa agidi okan buburu re" **<u>Jeremiah 18: 11-12.</u>** Mase ko Olorun, bikose ki o ko Satani ati awon ise re sile; mase fi aye fun Esu ninu aiye re, tabi ninu okan re. Mase tetisi etan ati arekereke ti o le mu o sina, ti yio si jeki o ko awon ikilo Oluwa.

**<u>A ko Josefu:</u>** Awon arakunrin Josefu ko gegebi olori/asiwaju, nitori awon ala ti a fihan fun u lati odo Oluwa. Awon wonyi ta Josefu fun awon onisowo ara Ismaeli, awon onisowo Ismaeli si ta josefu gegebi alagbase/eru fun Potifari

ijoye Farao, eniti ise olori eso. A fi Josefu sinu tubu, sugbon ni ikehin o di alase ile Egipti. Awon arakunrin Josefu wa lati ile Kenaani si Egipti lati teri won ba niwaju re, nwon si bu ola fun u **Genesisi 37-42; 43: 26-28.** Gbogbo okan ti o ti ko o sile, nitori ogo ati ileri Olorun ninu aiye re, yio padawa lati teriba niwaju re, nwon o si dobale fun o.

**Ikosile ti Mose:** Awon omo Israeli ti ko Mose sile, ki Olorun to yan a, gegebi asiwaju tabi olori ti yio mu Israeli jade kuro ni Egipti. Ni ojo kan Mose jade lo, o ri ara Egipti kan o nlu Heberu kan, okan ninu awon arakunrin re; Mose si pa ara Egipti na. Nigbati o jade lo ni ojo keji, o ri awon okunrin meji ara Heberu nba ara won ja: o si wi fun eniti o firan wipe, ese ti iwo fi nlu egbe re?. Okunrin na dahun wipe, "Tali o fi o je olori ati onidajo lori wa? Iwo fe pa mi bi o ti pa ara Egipti?" **Eksodu 2: 11-14.** "Mose na yi ti nwon ko, wipe tali o fi o je olori ati onidajo? On na li Olorun ran lo lati owo angeli ti o farahan a ni igbe, lati se olori ati oludande. On li o mu won jade, lehin igbati o se ise iyanu ati ise ami ni ile Egipti **Ise awon aposteli 7: 35-36.** Olorun yio so o di kose-mani fun gbogbo okan ti o ti ko o sile.

Isele miran tun sele nigbati Kora, Datani ati Abiramu pelu adotalerugba awon olokiki ati oloruko ninu ijo enia Israeli sote si Oluwa ati awon eni-mimo re (Mose ati Aaroni) **Numeri 16: 1-5, 11.** Nigbana ni Mose wipe "Nipa eyi li enyin o mo pe Oluwa li o ran mi lati se gbogbo ise wonyi; ati pe emi ko se won lati inu ara mi wa. Bi awon okunrin wonyi ba ku bi gbogbo enia ti iku, tabi bi a ba si be won wo bi ati ibe gbogbo enia wo; nje Oluwa ki o ran mi. Sugbon bi Oluwa ba se ohun titun, ti ile ba si la enu re ti o si gbe won mi, pelu ohun gbogbo ti ise ti won, ti nwon si sokale lo si ipo-oku laaye; **nigbana enyin o mo pe awon okunrin wonyi ti gan Oluwa**" **Numeri 16: 28-30.** Bi Mose se pari siso oro wonyi, ile ya enu re, o si gbe won mi pelu gbogbo ohun ini won **Numeri 16: 31-33.** Mase ko Oluwa ati awon eni-mimo re sile, ki ajalu-ibi maba de ba o.

**Awon enia Jefta ko o sile:** Awon arakunrin Jefta ko o, nitori o je omo pansaga. Awon arakunrin re le jina wipe "Iwo ki yio jogun ni ile baba wa; nitoripe omo ajoji obinrin ni iwo ise" **Awon onidajo 11: 1-3.** Ni igba isoro, awon agba Gileadi to Jefta wa, nwon si wipe "Wa je olori wa, ki awa ki o le ba awon omo Ammoni ja". Jefta si dahun wipe "Enyin ko ha ti korira mi, enyin ko ha ti le mi kuro ni ile baba mi? E si ti se ti enyin fi to mi wa nisisiyi nigbati enyin wa ninu

iponju?" Awon agba Gileadi si ba se adehun wipe bi Oluwa ba fi awon omo Ammoni le o lowo, ti o si bori won; ki ise wipe awa yio gba o pada nikan, sugbon iwo ni yio je asiwaju wa **Awon onidajo 11: 4-11.** Oluwa gbo adura ti Jefta gba ni Mispa, on si segun awon omoAmmoni, beni o di asiwaju awon enia Gileadi **Awon onidajo 11: 29-33.** Olorun yio so o di asiwaju ati alakoso awon enia ti won ti ko o sile, ti won si korira re.

## Awon eniti Oluwa kosile

Ohun ti o buruju ti o le sele si enikeni ni ki Oluwa Olorun eleda ko enia sile, ki o si fi elomiran ropo onitohun. Nitorina, kiyesara, mase dawole ohunkohun ti yio mu ki Oluwa ko o sile, ki o si kehin si o.

**Olorun ko Esu sile:** Esu subu ni iwaju Olorun nitori igberaga, iro ati arekereke. Torina, a le jina kuro ninu orun sinu aiye **Isaiah 14: 12-15.** Bi o ba fe ki Olorun mu oro re ti o wipe "Emi ko ni fi o sile, beni Emi ko ni ko o" se ninu aiye re; mase je agberaga tabi alafojudi, mase je agabagebe tabi eletan. Bibeli wipe "Ogun si mbe li orun; Mikaeli ati awon angeli re ba dragoni na jagun; dragoni si jagun ati awon angeli re. Nwon ko si le segun; beni a ko si ri ipo won mo li orun. A si le dragoni nla na jade, ejo lailai ni, ti a npe ni Esu, ati Satani, ti ntan gbogbo aiye je, a si le ju si ile aiye, a si le awon angeli re jade pelu re" **Ifihan 12: 7-9.** A gbadura wipe, iwo koni di eni-itanu ni iwaju Olorun, beni o koni di eni-ikosile ni iwaju awon orun. Bi o ko ba fe subu lati inu ogo sinu ekuru, mase ko Oluwa sile, sugbon ma se awon ohun ti inu re dun si i.

**Olorun ko Saulu ni oba:** Olorun ko Saulu gegebi oba lori Israeli, nitoriti o da Agagi oba Amaleki ati awon ohun ini awon Amaleki ti o dara si i; nipa iwa yi saulu se aigboran si Oluwa, ko si tele oro re. Oro Oluwa to Samueli wa wipe "Emi kanu gidigidi ti emi fi Saulu joba: nitoriti o ti yipada lehin mi, ko si mu oro mi se." O si ba Samueli ninu je gidigidi; on si kepe Oluwa ni gbogbo oru na **1 Samueli 15: 10-11.** Fun idi eyi, Samueli so fun Saulu pe "Nitoripe isote dabi ese afose, ati agidi gegebi iwa buburu ati iborisa. Nitoripe iwo ko oro Oluwa, on si ko o li oba" **1 Samueli 15: 23.** E jeki a kiyesara, ki ibanuje ati abamo maba gbehin aiye wa, bi ti oba Saulu.

Lakotan, nigbakugba ti a ba korira re, tabi ti a ba ko o sile nitoriti o se awon ohun daradara; mase kominu, sugbon teramo awon ohun ti o nse ti inu Oluwa

dun si i: nitoripe kosi woli/eni-mimo ti a tewogba ni ile baba re, li Oluwa wi **Luku 4: 24.** Mase jeki iberu ikosile mu o lati se amulu-mala, ki o si se awon ohun ti inu Oluwa kodun si.

**Edidi: Orin Dafidi 118: 22:** Okuta ti awon omole ko sile li o di pataki igun ile.